“Ọlọhun fi àkàwé kan lélẹ nipa ojú ọnà tàárà kan

Lati ọdọ An-Nawwaas ọmọ Sam’haan Al-Ansaariy- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pé: “Ọlọhun fi àkàwé kan lélẹ nipa ojú ọnà tàárà kan, ti ògiri méjì wa ni ẹgbẹ méjèèjì ojú ọnà naa, ti àwọn ẹnu ọnà ti wọn ṣí silẹ wa nibẹ, ti àwọn aṣọ ẹnu ọnà ti wọn dà wálẹ si n bẹ ni àwọn ẹnu ọnà naa, olupepe kan n bẹ ni ẹnu ọnà ojú ọnà naa ti n sọ pé: Ẹyin èèyàn, gbogbo yin ẹ ko sínú ọnà naa, ẹ má ṣe wọ́, ati olupepe kan ti n pepe lati òkè ọnà naa, ti o ba ti wa fẹ ṣí nǹkan kan ninu awọn ojú ọnà yẹn, o maa sọ pé: Káì, ma ṣi i, ti o ba fi le ṣi i wàá wọ́, ojú ọnà naa ni Isilaamu, àwọn ògiri méjèèjì naa ni: Awọn ààlà Ọlọhun, àwọn ẹnu ọnà ti wọn ṣi silẹ ni: Awọn nǹkan ti Ọlọhun ṣe ni eewọ, ẹni tí n pepe ni orí ojú ọnà naa ni: Tira Ọlọhun, ẹni tí n pepe ni òkè ojú ọnà naa ni: Oníwàásù Ọlọhun ninu ọkàn gbogbo Musulumi”.

[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ahmad ni wọn gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe: Ọlọhun fi àkàwé lélẹ fun Isilaamu pẹlu ojú ọnà tàárà ti o tẹ ti kò wọ́, tí ògiri méjì n bẹ ni ẹgbẹ méjèèjì ojú ọnà naa ti wọn rọkirika rẹ, àwọn méjèèjì náà ni àwọn ààlà Ọlọhun, àwọn ẹnu ọnà ti wọn ṣi silẹ n bẹ láàrin ògiri méjì yii, àwọn naa ni àwọn nǹkan ti Ọlọhun ṣe ni eewọ, àwọn aṣọ ẹnu ọnà n bẹ ni àwọn ẹnu ọnà naa ti ko nii jẹ ki ẹni tí n kọjá ri ẹni tí ó wà ninu rẹ, olupepe kan si n bẹ ni ìbẹ̀rẹ̀ ojú ọnà naa ti n dari àwọn èèyàn ti o si n sọ fún wọn pé: Ẹ maa rìn lọ lori ẹ lái fi si etí ati ẹgbẹ́, olupepe yii ni tira Ọlọhun, olupepe mìíràn tun wa ni òkè ọnà naa; olupepe yii, gbogbo igba ti ẹni tí n rìn ni oju ọna naa ba ti fẹ ṣi aṣọ ẹnu ọnà yẹn díẹ, o maa jagbe mọ́ ọn, o maa wa sọ fún un pé: Ó ṣe fún ẹ, o ò gbọdọ ṣí i! Ti o ba ṣi i, waa wọ inú ẹ, o ò si nii ni ikapa lati kọ̀ fun ara rẹ lati má wọlé, olupepe yii ni oníwàásù Ọlọhun ninu ọkan gbogbo Musulumi.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65049